Ọrọ̀ ti Ọlọhun nífẹ̀ẹ́ si julọ mẹrin ni: SUBHAANALLAH, ati ALHAMDULILLAAH, ati LAA ILAAHA ILLALLOOH, ati ALLAHU AKBAR, èyíkéyìí ti o ba wù ọ ni o le fi bẹ̀rẹ̀ nínú wọn”

Láti ọ̀dọ̀ Samurah ọmọ Jundub- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pé: Ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: Ọrọ̀ ti Ọlọhun nífẹ̀ẹ́ si julọ mẹrin ni: SUBHAANALLAH, ati ALHAMDULILLAAH, ati LAA ILAAHA ILLALLOOH, ati ALLAHU AKBAR, èyíkéyìí ti o ba wù ọ ni o le fi bẹ̀rẹ̀ nínú wọn”.

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé pe ọ̀rọ̀ ti Ọlọhun nífẹ̀ẹ́ si julọ mẹ́rin ni: SUBHAANALLAH: O n túmọ̀ sí fifọ Ọlọhun mọ́ kuro nibi gbogbo adinku. ALHAMDULILLAAH: Oun ni fífi pípé ròyìn Ọlọhun pẹlu ìfẹ́ Rẹ ati gbigbe E tobi. LAA ILAAHA ILLALLOOH: Ìtumọ̀ rẹ ni: Ko si ẹni ti a le maa jọ́sìn fun ni ododo ayafi Ọlọhun. ALLAHU AKBAR: Ìtumọ̀ rẹ ni: O gbọnngbọn, O si tobi, O si ni agbara ju gbogbo nnkan lọ. Ati pe ọla rẹ ati ríri ẹsan rẹ, ko beere fun títò ó tẹle ara wọn ti a ba n pe wọn jáde lẹnu.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/5475